Musulumi ni ẹni ti awọn musulumi la nibi ahọn rẹ ati ọwọ rẹ, ati pe Al-muhaajiru ni ẹni ti o yan nkan ti Ọlọhun kọ lodi

Lati ọdọ Abdullāh ọmọ Amru - ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji - lati ọdọ Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - o sọ pe: «Musulumi ni ẹni ti awọn musulumi la nibi ahọn rẹ ati ọwọ rẹ, ati pe Al-muhaajiru ni ẹni ti o yan nkan ti Ọlọhun kọ lodi».
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe dajudaju musulumi ti Isilaamu rẹ pe oun ni ẹni ti awọn musulumi la nibi ahọn rẹ, ko nii bu wọn, ko si nii ṣepe fun wọn, ko si nii sọ ọrọ wọn lẹyin, ko si nii maa fi ahọn rẹ tan èyíkéyìí ninu awọn iran ṣuta ka laarin wọn, Ti wọn si tun la ni ọwọ rẹ, ko si nii tayọ ẹnu-ala si wọn, ko si nii gba awọn dukia wọn ni ọna aitọ, ati nkan ti o jọ ìyẹn, Ati pe Al-muhaajiru ni ẹni ti o gbe nkan ti Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ṣe leewọ jusilẹ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/10101